# OYO STATE HOUSE OF ASSEMBLY, IBADAN
## FEDERAL REPUBLIC OF NIGERIA

8TH ASSEMBLY
2ND SESSION
NO. IKEFA

# VOTES AND PROCEEDINGS

**OJORU, OJO KETA, OSU KEJO, ODUN EGBEWA LE MERINDINLOGUN**

1.0 Ilé jókǒ ní aago mejila ku iseju merinleogun, Alága Ilé jókòó, Asofin K.H. Subair (Gúsù Iwo Oorún Ìbàdàn Kinnì), Olórí Ọmọ Ẹgbẹ́ tó pọ̀jù si gba adura.

## 2.0 ÀKỌSÍLẸ̀ ORÚKỌ:

### 2.1 ÀWỌN TÍ O WÁ:

| | | |
|---|---|---|
| (i) | Ọlọ́lá Aṣòfin A. M. Adéyẹmọ- | Alága Ile (Ilà Oorùn Ìbàrapà), APC |
| (ii) | Aṣòfin A. Musah - | Igbakeji Alaga( Ìwọ̀ Oorùn Sakí), APC |
| (iii) | Aṣòfin K. H. Subair - | (Gúsù Iwo Oorún Ìbàdàn Kinnì), APC |
| (iv) | Aṣòfin S. O. Àjànàkú - | Alága Ìgbìmọ̀ gbogbo Àwọn Aṣòfin (Gúsù Ìwọ̀ Oorùn Ìbàdàn Kejì), APC |
| (v) | Aṣòfin O. A. Oyatokun - | Igbá Keji Olórí Ọmọ Ẹgbẹ́ tó pọ̀jù lo (Afíjíó), APC |
| (vi) | Aṣòfin J. A. Olaleru - | Igbá Keji Akójanu Ilé, (Kajola) APC |
| (vii) | Aṣòfin G. J. Oyekola - | Akójanu Ẹgbẹ (LP) Àtìbà, |
| (viii) | Aṣòfin S. A. Olalere - | Ìdo, (APC) |
| (ix) | Aṣòfin S. O. Oguntade - | Ẹgbẹ́dá, (ACCORD) |
| (x) | Aṣòfin A. Oseni - | Ìrẹ́pọ̀ ati Ọlọ́runsógo, (APC) |
| (xi) | Aṣòfin (Iyaafin) B. O. Agbaje- | (Ariwa Ìbàdàn Kínní), APC |
| (xii) | Asofin A. A. Adeleke - | Ìṣẹ́yìn ati Ìtẹ̀síwájú, (APC) |
| (xiii) | Asofin M. A. Wahab - | Oluyole, (APC) |
| (xiv) | Aṣòfin R. A. Jimoh - | Àríwá àti Àarin Gbùngbùn Ìbàrápà, (APC) |
| (xv) | Aṣòfin (Iyaafin) B. O. Oladeji- | Aríìwǎ Ògbómọ̀ṣọ́, (LP) |
| (xvi) | Asofin B. S. Badmos - | Akínyẹlẹ Kejì, APC |

| | | |
|---|---|---|
| (xvii) | Aṣòfin A. K. Ọlọ́ya | - Akójanu Egbe (Àríwá Ilà Oorùn ÌbàdànKínní), ACCORD |
| (xviii) | Aṣòfin P. O. Oyetunji | - (Ògo-Olúwa àti Sùrúlèré (LP) |
| (xix) | Aṣòfin B. A. Azeez | - Ọ̀nà-Àrà, (ACCORD) |
| (xx) | Aṣòfin O. S. Akande | - Gúsù Ògbómòsò (LP) |
| (xxi) | Aṣòfin A. A. Ige | - Gúsù Ila Oorun Ìbàdàn Keji), ACCORD |
| (xxii) | Aṣòfin M. A. Sangodipe | - Ìlà Oòrùn Ṣakí àti Atisbo, APC |
| (xxiii) | Aṣòfin A. F. Adesina | - Gúsù Ìla Oòrun Ibadan Kínní, (ACCORD) |
| (xxiv) | Aṣòfin M. O. Olagunju | - Ìwọ̀ Oòrùn Àti Ilà Oorùn Ọ̀yọ́, (ACCORD) |
| (xxv) | Aṣòfin S. A. Okunlola | - Ìwájọ̀wá, (APC) |
| (xxvi) | Aṣòfin J. Oyebamiji | - Akínyẹ́lẹ́ Kínní, (ACCORD) |

2.2 **ÀWỌN TÍ KÒ WÁ**:

| | | |
|---|---|---|
| (i) | Aṣòfin J. O. Ojo | - Olórí Ọmọ Ẹgbẹ́ tó kéré jú (Oriire), LP |
| (ii) | Aṣòfin W. O. Akinmoyede | - Akójanu Ilé (Lagelu), APC |
| (iii) | Aṣòfin A. A. Ọládípọ̀ | - Akójanu Ẹgbẹ APC, (Aríìwá-Iwọ̀ Oorùn Ibadan) |
| (iv) | Aṣòfin O. O. Ọláléyẹ | - Àríwá Ìbàdàn Kejì, (APC) |
| (v) | Aṣòfin A. W. Adéoyè | - Àríwá Ilà Oorún Ìbàdàn Kejì (ACCORD) |

## 3.0 FIFI ỌWỌ SÍ ÌWÉ ÀKỌSÍLÉ ÀTI ÌFẸNUKÒ ÌJOKO ÍLÉ:

Àlága Ilé se ìkéde wípé òun tí ye Ìwé Àkọsílè àti Ìfẹnukò Ìjoko Ọjọ́ Ìṣẹ́gun, Ọjọ́ Keji, Osù Kejo, Ọdún Egbewa le Merindinlogun, wo, ó sǐ bèèrè fún àtúnṣe.

Àbá wá wípé, "kí a gbà Ìwé Àkọsílẹ́ àti Ìfẹnukò ti Ọjọ́ Isegun, Ọjọ́ Keji, Osù Kejo Odun Egbewa le Merindinlogun wọlé" - Aṣòfin K. H. Subair (Gúsù lwo Oorún Ìbàdàn Kinnì), Olórí Ọmọ Ẹgbẹ́ tó pọ̀jù lọ.

Akéjì Àbá - Aṣòfin G. J. Oyekola, (Atiba), Akojanu Egbe (LP)

Ìbèrè wáyé pé sékí á gba Àbáá na wọlé?

**<u>Ìfẹnukò</u>** wáyé lórí Àba

## 4.0 GBÍGBA ÀKÀNSE ORIN ÌPINLE Ọ̀YỌ́ GẸGẸBI OHUN ÌDÁNIMỌ̀ PÀTÀKÌ:

Àbà wáyé pé Kí Ilé Sàgbéyèwò Àsàyàn Orin Ìpinle Ọ̀yọ́ láti mọ ríri ìwúlò rẹ̀ pẹ̀lú èrongbà làti gba gẹ́gẹ́bí ohun ìdánimọ̀ Pàtàkì tí a o maa kó ni gbogbo àpèjo Pàtàkì ní Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́: - Aṣòfin A. M. Adéyẹmọ- (Ilà Oorùn Ìbàrapà), Alága Ile. Èyí tí ọ́jé kíkà sí Ilé lati odo Aṣòfin S. O. Àjànàkú(Gúsù Iwọ̀ Oorùn Ìbàdàn Kejì), Alága Ìgbìmọ̀ gbogbo Àwọn Aṣòfin

Akẹ́ji Aba: Asofin A. Músah (Ìwọ̀ Oòrùn Sakí), Igbákeji Alága.
Ibéèrè wayé pe, sé kí a gba Abáa náà wọlé fún ìjíròrò.
Àtúnse deba àkọlé Àbá náà bàyìí "GBÍGBA ÀKÀNSE ORIN ÌPÍNLẸ̀ ỌYỌ GẸGẸ́BÍ OHUN ÌDÁNIMỌ̀ PÀTÀKÌ"
Ìfẹnukò wayé láti sọ̀rọ̀ sí àbá náà
Ìjíròrò bẹ̀rẹ̀
Ìbéèrè wáyé pé se kí a gba Àbá náà wọlé.
**Ifenukọ** waye lori Abaa naa bayi wipe:

Kí Ilé pinnu "Láti:

(i) Gba Orin Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ (Ọyọ́ Anthem) gẹ́gẹ́ bí ohun ìdánimọ̀ pàtàkì;
(ii) Ro Ẹ̀ka Aláṣẹ Ìjọba láti ri wípé wọn nko Àsàyàn Orin Ọ̀yọ́ (Ọyọ́ Anthem) ní ìgbà gbogbo tí Ìjọba bá nse ètò Pàtàkì pẹlú ará ìlú, ẹlẹ́gbẹ́-jẹgbẹ́, àwọn oniṣẹ àdáni, àwọn onísòwò àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ;
(iii) Ro Ẹ̀ka Aláṣẹ Ìjọba nípasẹ̀ Ilé Iṣẹ́ Ìjọba ti Ẹ̀tọ Ẹ̀kọ́, Ìmọ̀ Sáyẹ́nsì àti Ìmọ̀ Ẹ̀rọ láti paá láṣẹ fún àwọn Ile Ẹ̀kọ́ Alákọ̀bẹ̀rẹ̀, Girama àti àwọn Ẹ̀kọ́ Àgbà láti máa ko Orin Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ ní ọjoojúmọ́, nígbà tí wọ́n bá nse àpéjọpọ̀ láràárọ̀ ati lórè, kóòrè pàápàá júlọ ni ìgbà tí wọ́n bá ní àwọn àkànse ètò bíi ere ìdáraya, ọjọ ìrántí àwọn ọmodé (27th May), ayẹyẹ ìjáde àwọn akẹ́kọ̀ àti ayẹyẹ ìrántí ọjọ́ ìgbòmìnira Orílẹ̀ Èdè wa (1st October) àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ;
(iv) Ro Àwọn ará ilé, ẹlẹ́gbẹ́ jẹgbẹ́, ọlọ́gbà jọgbà, àwọn olórin àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ láti máa kọ Orin Ìpínlẹ̀ Ọyọ nínú àwọn ètò wọn tí ó bá ṣe Pàtàkì;
(v) Ro Ẹ̀ka Aláṣẹ Ìjọba nípasẹ̀ Ilé Iṣẹ́ Ìjọba ti Ìròhìn, Àṣà àti Ìgbohùn Sáfẹ́fẹ́ àti Móhùn Máwòrán láti maa kọ Orin Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ Setí àwọn ará ìlú lóòrèkóòrè;
(vi) Ilé pinnu pé kí Orin Ìpínlẹ̀ Ọyọ máa jẹ́ kíko nibi Ìjókò Ilé Yorùbá Pónbẹ́lé;
(vii) Kí Ẹ̀ka Aláṣe se Ìwúrí tó yáàyì fún àwọn tí ó se àgbékalẹ̀ Orin Ìpínlẹ̀ Ọyọ́;
(viii) Ile Pinnu wípé kí eni tí ó se àgbékalẹ̀ Orin náà fi ara hàn ní iwájú Ìjókò Ilé tí ó jẹ́ Yorùbá Pónbẹ́lé lati se àyẹsí rẹ̀.

**ÀṢORỌ̀ ABALA KẸRIN (ẸSẸ̀ KINNI) ÌWÉ ÌLÀNÀ ÈTÒ TI ILÉ ÌGBÌMỌ̀ ASÒFIN ÌPÍNLẸ̀ ỌYỌ́**

"Àbáa wáyé "Wípé kí á so Abala Kẹrin (Ẹsẹ̀ Kínní) Ìwé Ìlànà Ètò Ti Ilé Ìgbìmọ̀ Asòfin Ìpínlẹ̀ Ọyọ́ rọ̀ láti jẹ́ kí Ilé Tẹ̀síwájú Nínú Ìjíròrò Rẹ̀ Síwájú Agogo Kan Ọ̀sán" – Asòfin O.A. Oyátókun (Afijio) Igbákejì Olórí Ọmọ Ẹgbẹ́ Tó Pọ̀júlọ
Akéjì Abá: Asòfin G.J. Oyekọla (Àtìbà), Akojanu Ọmọ Ẹgbẹ́ Labour
Ìbèrè wípé sé kí á gba Àbáa nâa wọlé jẹ́ àtẹ̀wọ́gbà.

5.0 **SÍSE ÀMÓJÚTÓ ÌWÀ ÀÌGBỌRÀN NÍ ILÉ ẸKỌ́ WA ÀTI WÍWÁ ỌNÀ LÁTI DÁ ÈTÒ ẸKỌ́ TÓ YÈ KOORO TÍÍ SỌ AKÊKỌ́ DI ALÁSEYỌRÍ ÀTI ỌMỌLÚÀBÍ PADÀ NÍ ÌPÍNLẸ̀ ỌYỌ́**

Àbá wáyé pé kí Ilé Jíròrò lórí Àwọn Ìṣẹ̀lẹ̀ Tó Nṣẹlẹ̀ Ní Ilé Ẹ̀kọ́ Alákọ̀bèrè àti Girama ti Ìjọba tí Múkí Iná Ẹkọ́ Jó Àjórẹ̀hìn àti bí Àwọn Akẽkó Kan T i Gbé Ìwà Ìbàjẹ́ Wọ̀ Bí Ẹ̀wù, Pẹ̀lú Èròngbà Láti Rọ Ẹ̀ka Aláṣẹ Láti Gbé Ìgébsẹ Láti Mú Ètò Ẹ̀kọ́ Ní Ọ̀kúnkúndùn – Asòfin S.A. Òkunlọlá (Ìwájọwà)
Akéji Àbá: Asòfin A. Oseni (Ìrẹ́pọ̀ ati Olórunsógo)
Ìbêrè wáyé pé, sé kí á gba Àbáa nâa wolé fún ìjíròrò?
Àbá wáyé pé kí Olùdá Àbá yí lọ se àtúnse Ìgbékalẹ̀ Àbá wọn láti le fún Ilé ní ànfààní láti mọ̀ bóyá Ìwà Ìbàjẹ́ èyí tí Àwọn Ọmọ Akẹ́kọ́ Ile Ìwé Wa Ńhù Nı Ilé fẹ́ẹ́ sọ̀rọ̀ sí tàbí Ìpò tí Àwọn Ilé Ẹ̀kọ́ Wa. - Asòfin G.J. Oyẽkọ́lá (Àtìbà),
Akéjì Àbá: Asòfin J. Oyebamiji (Akínyẹ́lẹ́ Kínní)
Àtakò Àbá wáyé pé kí Ilé tẹ̀síwájú ìjíròrò lórí Àbá yi torí pé ẹsẹ méjèèjì tí Aba yi ntọ́kasí ló wà ní ìbámu – Asofin S.A. Ọlálérè (Ido)
Akéjì Àbá: Asòfin B.A. Azeez (Ònà-Àrà)
Ìbêrè wáyé
**Ìfẹnukò** sì wáyé pé kí Oluudaba yí lọọ sẹ àtúnse lórí Àgbékalẹ̀ rẹ̀ láti fún Ilé ní Ànfààní láti mẹ́nu baà wọn ìwà ìbàjẹ́ tí ó gogò láàrin àwọn akẹ́kọ́ níbi Ìjókó Ilé eyí tí ó jẹ́ Yorùbá Pọ́nbélé míràn tí yóò wáyé lẹ̀yìn eléyí.

6.0 **ÀSORỌ̀ ÌJÓKÒ ILÉ:**

Àbá wáyé, "Wípé kí á sọ Ìjókò Ilé rọ̀ di Ọ̀la, Ọjọ́bọ̀, Ọjọ́ kẹ́rin, Osù Kẹjọ, Ọdún Ẹgbẹ̀wá le mẹ́rìndínlógún ní agogo mẹ́wà òwúrọ̀" - Asòfin O.A. Ọyátókun (Afijió), Igbákejì Olórí Ọmọ Ẹgbẹ́ tó pọ̀ júlo.
A so ijòkó Ilé rọ̀ ní aago kan kọjá ìsẹ́jú marun.

**Ọlọ́lá-Aṣòfin A. M. Adéyemo,**
Alága Ilé.